# Ti ẹnikẹni ninu yin ba wọ masalaasi, ki o yaa ki rakaa meji siwaju ki o to jokoo

Lati ọdọ Abu Qataada as-Sulamiyy – ki Ọlọhun yọnu si i – dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – sọ pe: «Ti ẹnikẹni ninu yin ba wọ masalaasi, ki o yaa ki rakaa meji siwaju ki o to jokoo».
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe ẹni ti o ba wa si masalaasi ti o si wọle sibẹ ni eyikeyii asiko, ati fun èyíkéyìí erongba, ni ojukokoro lati ki rakaah meji siwaju ki o to jokoo, ati pe awọn mejeeji ni rakaah meji kiki masalaasi.